IKEDE PATAKI

A fi eyi kede fun awon onkawe wa pe, IWE IROHIN YORUBA yio di kobo meta (3d.) ni ose ti o mbo gegebi awon oniwe Irohin elegbe wa ti o njade lojolojoju/mo ti so tiwon di kobometa (3d.) bakanna.

*Olotu*

# Irohin Yoruba

NO. 931 WEDNESDAY May 1—Tuesday May 7 1963 KOBO MEJI 2D

Print your Yoruba litratures with the correct accent types at

**Remilekun Press**
Agege Motor Road Atewolara Box 69, Mushin, Lagos.

# IYAWO AFESONA KAGBAKO

**Adajo agba kotu giga kan ni Ibadan Ogbeni Olujide Somolu palase pe Omidan Kehinde Jeyfous eni odun mokandilogun ti o nsise atewe ko gbodo fe Ogbeni Jinadu Jimmy Ogunbona ayafi ti o ba di eni odun mokanlelogun.**

Ohun ti o fa ase idalowoko fun tokotiyawo na ni pe, Ogbeni S. A. Jeyfous eni odun marunlelogota ti ise baba iyawo afesona tako eto igbeyawo omo re pelu Jinadu Jimmy Ogunbona niwaju adajo. O di ojo kokanlelogun ti nwon ti towo bo iwe igbeyawo, sugbon nigbati o ku ojo marun ki ojo igbeyawo pe ni kotu ba tu u ka.

Ogbeni Ogunbona ko si ninu kotu ni ojo ojo'Ru ti ise ojo kerinlelogun osu kerin odun yi nigbati adajo gbesele eto igbeyawo won.

Adajo bere pe, kinise ti Ogbeni Ogunbona ko fi wa si kotu, sugbon Ogbeni Jeyfous so fun adajo pe, "emi ati iya Kehinde ko tile l'oju ganni re". Were ni Kehinde dasi oro na, o si so fun adajo na pe, "Jimmy mbe l'Eko, mo gba pe nko ti to di eni oko nitoripe ojo karun osu kerin odun 1944 ni nwon bi mi.

### AFIYESI

Ninu idahun si ibere miran lati enu adajo agba na, Ogbeni Jeyfous oludasile ile ise hoteli ati eniti o ngba owo ifehinti ni, "dajudaju akata mi omo mi yio wa."

Ninu idajo re, adajo agba Ogbeni Somolu ni, iyalenu ni o je fun mi lati rii pe Kehinde fe wo ile oko ni yajoyajo nitorina mo gbese le eto igbeyawo na Ogbeni Ogunbona ko si gbodo gbe Kehinde ni iyawo ayafi ti o ba di omo odun mokanlelogun." Siwaju sii adajo agba na kilo fun Ogbeni Ogunbona pe ko gbodo fe Kehinde laiko si imo obi re ati ti Ijoba. O ni, itapa si ase kotu yio fi iya je Ogbeni Ogunbona.

Gere ti Ogbeni Jeyfous jade ni kotu ni o ti beresi leri pe ti awon oniwe-irohin ba fi le gbe irohin igbesele eto igbeyawo omo on jade ninu iwe irohin won on yio han won ni kooru egnmo.

*Z-E-E-K!*



Aworan oke yi ni igbati Gomina agba Naijiria ati iyawo Gomina Ijoba Ipinle Iwo Orun Naijiria iyaafin Fadahunsi jijo njo mukunmuke ninu "Gbogan" "Western Hall" Ibadan.

Wo oju ewe iwe karun fun irohin ati aworan nipa irin aje Dokita Azikiwe.

# KANIKE T'ORI OOKAN W'OGBE

Afoju alagbe kan ti oruko re nje Audu Sokoto takiti wonu odo Kaduna nigbati ohun ati alagbe keji re jijo fija peeta ni ojo abameta ti ise ogunjo osu kerin odun yi

Alafojuri kan ni o so bi kobo kan se da ija sile larin Audu Sokoto ati Yinusa Gusau eyiti okunrin kan fi se awon mejeji lanu. Siwaju sii, alafojuri na so pe, bi Sokoto ti njijadu lati ja kobo na gba mo Gusau lowo, ni o ba talu kukute igi kan leba ese afara, o si takiti sinu odo.

Opelope awon alanu enia ti o oyo ninu odo, iba ku si omi.

# ALUKO TUNA ASIRI ONABAMIRO

**Dokita Aluko ka awon akosile ti o wa ninu iwe Asiri re fun Adajo Agba kotu giga kan l'Eko ni ojo Eti ti ise ojo kokanlelogun osu kerin odun yi nigba ti o njeri gbe Oloye Awolowo ninu ejo idite mo oba Ilu Oyinbo lati doju Ijoba dele ti Ijoba mba on ati awon elegbe re se.**



Oloye Obafemi Awolowo

Olori agbefoba Ogbeni Boonyamin Kassim nfi oro wadi oro lenu Dokita Aluko nigbati o so fun Adajo agoa kotu giga Eko na pe "Gobgbo oro ajumoso emi ati Dokita Sanya Onabamiro ni mo ko sile laseko rogbodiyan ti o sele ninu egbe Afenifere ni Ipinle Iwo Orun Naijiria.

Dokita Onabamiro ti fi igba kan je eleri fun Ijoba ninu ejo idite na. Ninu oro re, Dokita Aluko so pe, 'Dokita Onabamiro wa si odo mi lati wadi awon ti o wa ninu egbe Action Group Tactical Committee, o si seleri pe on ko fe se Oloye Awolowo ni on se nwadi bee, mo si so fun pe nko mo nkankan nipa oro Tactical Committee na nitoripe emi ki i se omo egbe Afenifere. Dokita Onabamiro si tun so fun mi pe oruko on ko si ninu awon ti yio jeri ni kotu nipa oro ti o jemo ti ejo idite si oba na."

Siwaju sii, Dokita Aluko so pe "nigbati mo ka eri ti Dokita Onabamiro lo je niwaju Adajo Agba kotu giga l'Eko ni osu kejila odun ti o koja yi, inu bi mi, okan mi si gbogbe gidigidi nigbati o so fun Adajo agba na pe okan ninu awon omo egbe Tactical Committee ni on ise lehin igbati o ti wa fi oro lu mi lenu gbo oro nipa egbe na.

Eyi wa fi han mi gbangba pe, nse ni Dokita Onabamiro wa fi ogbongbon ati ereero wadi awon egbe na lenu mi ki o ba le mo eri ti yio je lodi si

Wo oju ewe keta

# SAMMI R'AJA INU OKE

Pelu omije loju ni Jimoh Sammi fi nso fun adajo agba na pe "Nko mo pe garawa omi meta ni Verrisimo ta fun mi ni adota ponun dipo garawa oti robirobi. Adehun pe ki nsan adota ponun ninu ogota ponun fun garawa oti robirobi meteta na ni a jijo se pe ti mo ba si taa tan, ngo fun ni owo re ti o ku."

### IWA JAMBA

Ogbeni Sammi ni lesekese ti o di mimo fun on pe omi lasan ni o wa ninu awon garawa meteta na ni on ba ranse si Verrisimo pe ki o foju kan on. O ni, nigbati o de o beresi be on pe on yio san owo na pada.

Ninu oro awijare re niwaju Adajo, Verrismo ni, "ejo adunrunmo ni nwon ro mo mi nkan ti o si faa ni pe, mo ko jale lati fe Abeo ti ise omo Ogbeni Sammi."

# llu

Adisa, Miinsta Alako eto Irohin. Nse ni opa nlagun yobo, ti nu awon enia sehin ki Agba ba le ri aye koja ki ti o da pada funoro bo lati enu Akarigb Agba na ni "Naijiria o owo ti o sese nhu siyi, eyi ki o je ohun iru asese dide oriel o si jeki awon asiwa- o pe "ikoko ti yio je re yio gona. A nilati i asiwaju, ko si yeki okan ba wa nigbati i awon aiswaju wa ba ori ise iselu. Olunko- o wu ki o Ide de, ko ni fasehin lati opo fun idagbasoke won, ki awon paapa ojuse tiwon gegebi pataki ni Africa."

a-Agba na ni "Koni i ibewo mi si Shaga- toripe on ni o je ilu mo nilati ya ninu irin ajo mi si Ipinle n, mo kan saara si mo ati agbegbe re pe ni awon enia nlanla para lonakona lati so Naijiria di alagbara a. Adura mi ni pe ko o."

e ni Akarigbo ti so pe ti olododo enia ni Azikiwe ise. O sisadur n pe, lagbara Oluwa ododo ati otito inu a iwo ati irandiran re vaju si i Akarigbo ni be ni ibewo Gomina- je fun awonn enia ati gbegbe re nitori akoko ti Gomina- ilu na wo.

ipade ti Ibadan vere kyuare nibiti Oloye ati igbakeji re Ogbe- Kayode pelu awon metadilogbon ti wa mina Agba na. Lati ote ayokele won siti owo lo titi de Ile Asfin Iwo Orun ni ejila abo osan.

a Ipinle Iwo Orun Olola Odeleye si wa pade re pelu, i o ye awon soja ti o a Ile Igbimo Asofin ibewo re si Ipinle na

enia ja-nkanjanka ti nan Gomina-Agba na ni G. Maeghe asoju o wa ni "Ibadan, R. I. D. Jasper, asoju ees ti o wa ni Ipinle n Bisoba Finn alako- Aguda ati Eni-owo Jadesinmi ti o ndele owo S. O. Odutola.

ti Dokita Azikiwe ola Fadahunsi ti jijo an tan, ni o ba lo oo a ti "Port Harcour ati Western Rovers".



# Loya kan lugbadi ofin

Adajo kotu abA kan Oloye Inko-Tariah ju Uzockukwu Eyemonye amofin kan si ewon osu meta tabi ki o lo fi ogota poaun tanran fun esun enia lilu.

Esun ti olopa muu wa si-waju adajo ni pe, ni ojo keje osu kejila odun ti o koja yi ni Egemonye lu Ogbeni Dimkpa Osuagwu ti o nse ise isegun enia dudu kan, o si faa ni agbondo isale ya nitoripe o

ko jale lati fi moto re gbe amofin na. Pataki ohun ti o fa ija na ni pe, bi Egemonye ti nko nomba moto ayokele onisegun na sile ninu iwe kekere kan, ni Osagiwe ba jaa gba mo lowo, o si juu nu.

Ninu oje awijare re, Ege-monye so jun adajo pe, Osagwu ni o koko lu on, ki on papa to luu pada. Adajo ni on ko gba ejo re gbo, a fi ejo ti agbefoba.

Arufin na si ti pe ejo ko-temilorun.

**Aworan yi ni igbati Gomina agba Naijiria ati omo Oloye S. L. Akintola Olotu Ipinle Iwo Orun jimjo njo.**

**Oba T. M. Ogunlewe Ade/borin wa Igbogbo se eleketa ninu Ijo na. Ajoyo na ko se fenu so.**

**Aworan apa otun yi ni igbati awon Oluko aba ati awon oworan nyombo Gomina agba Naijiria Dokita Azikiwe bi o ti nwo moto ayokele re lo si Unifasity Ife. Eni ti o joko legbe otun re ninu moto ayokele ni Purofeso Ajose Oluko agba Unifasity na.**



## Igbeyawo Rosanwo dun

Irohin ko to afojuba ni igbeyawo ti Ogbeni J. O. Rosanwo se ni Yaba Baptist Church ni ojo Aiku ti ise ojo kokanlelogun osu kerin odun yi. Kete ti nwon se isin Igbe-yawo na ni awon alabaseye ba Ogbeni Rosanwo lo si ile egbon re Dokita Rosanwo ni nomba 12, Akinhanmi Street, Suru Lere nibe ni nwon ti pese jije ati mimu de won.

Orekelewa Iyawo Bernice Ola ni iyawo elese osun na. Ehin iyawo ko ji mo eni o. Ase.





